# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRỌ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 561 SATURDAY, MARCH 21, 1964 (2D)


## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Yio Se Ipade

MUSHIN:— Lati bi Ọjọ mẹta ni awọn ara Mushin ti ngmura sile ti nwọn si ti nreti awọn alejo Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre l'okunrin ati lo'binrin ti nwọn fẹ se ipade pataki kan ni nomba 23, Awoyọkun Street, Mushin ni Ọla Ọjọ Aiku ti iṣe Ọjọ kejilelogun Oṣu yi ni deede agogo mẹrin irọlẹ.

Oniwe irohin wa kan fi ye wa ni alẹ ana wipe awọn Ọba, Ijoye, Dokita Amofin, Olukọ—agba, ati awọn Minista pẹlu awọn enia sarakisaraki ni nwọn ti bẹrẹsi de si Mushin lati alẹ ana fun ipade ti awọn Ọmọ ẹgbẹ na fẹ ṣe ni irolẹ Ọla.

Ninu awọn enia jankanjankan ti yio sọrọ ninu ipade awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwọn fẹ ṣe ni ọla ni Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ ẹniti gbogbo aiye mọ apele orukọ rẹ ni "Aiyekotọ", Ọgbẹni J. A. Ọdẹku, akọwe Agba ẹgbẹ Afẹnifẹre, Olu Ọba Mushin, Olu Ọba Isọlọ, Alhaji Obisẹsan, Alhaji D. S. Adegbenro ati awọn miran.

Oniwe irohin wa Ejon'gboro yio lọ si ibi ipade na, gbogbo ohun ti nwọn ba sọ, ẹ o ma a gbọ ninu iwe irohin wa ni ọtunla.

# ALAKOSO IJỌBA GẸẸSI BA ILE IGBIMỌ SỌRỌ

EKO:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko gba ero fun ọgọgunlọgọ ọkẹ aimoye enia ti o wa sinu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ni ana ọjọ Ẹti ti iṣe ogunjọ osu yi, nigbati Ọlọla Alec Douglas-Home Alakoso Ijọba Gẹẹsi fi mba Ile Igbimọ na sọrọ.

Ọlọla Alec-Douglas Home fi ye gbogbo Ile Igbimọ na wipe o jẹ ohun idunnu fun on lọpọlọpọ lati ri wipe on ni anfani lati wa ni Naijiria ni asiko yi ati paapaju'ọ lati wa ni Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ki on si maa ba wọn sọrọ.

Ọlọla Dauglas-Home ṣe alaye pe yio jẹ ohun to dara lọpọlọpọ pe Orilẹ-ede Ijọba Gẹesi tun wa ni irẹpọ pẹlu Orilẹ ede Naijiria ju ti atẹhin wa lọ.

Alec Dauglas-Home ni ohun nla ati iyi ni o jẹ fun enia lati jẹ ẹniti awọn enia ilu rẹ yio yan lati dibo fun lọ si Ile Igbimọ Asofin.

O ni ẹnikẹni ti awọn enia rẹ ba dibo yan si Ile Igbimọ Asofin Ijọba, iba ṣe ti Apapọ Ijọba, tabi Ijọba Ipinlẹ tabi Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ, orire ni Oluwarẹ ṣe

### IBEJI ORIRE

O wa ṣe alaye siwaju wipe, ibeji orire ni o jẹ fun on loni lati le wa ba Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba ati awọn agba Oṣelu sọrọ loni.

Ati paapa julọ ohun ayọ ni Ipe ti Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria pe On lati wa ṣe abẹwo Orilẹ-ede Naijiria ni asiko yi

Ọlọla Alec Douglas-Home tun se alaye iru iwa ti oyẹ awọn ọmọ ile Igbimọ lati ma a hu ki ifẹ isọkan ati idagbasoke ole ba wa lorilẹ-ede kan tabi ekeji.

Onirohin wa kan fi ye wa wipe bi Ọlọla na ti sọrọ tan ni gbogbo ile na ho ge e, ti nwọn si patẹwọ.



**Ọlọla Alec Douglas-Home** K. T., M. P.,
ALAKOSO IJỌBA GẸẸSI

Ni deede agogo mẹjọ owurọ ni awọn ero ti parojọ si iwaju Ile Igbimọ Aṣofin na lati wa woran.

Ko si pẹ pupọ lẹhin na ni awọn Minista, Dokita Adajọ agba ati awọn ọmọ Ile Igbimọ na pẹlu awọn ti o wa woran bẹrẹsi de.

Irohin fi ye wa wipe awọn omọ Ile Igbimọ agba oṣelu ni nwọn pelọpọ wa sinu Ile Igbimọ ti Ọlọla na si ba gbogbo wọn sọrọ.

Lẹhin ti o pari ọro tan, eyiti o sọ fun ọgbọn iṣẹju, o bẹrẹ ni agogo mẹwa owurọ, o si pari ni agogo mẹwa abọ, ni o ba jade lọ.

Ṣugbọn nigbati yio fi jade, alaga Ile Igbimọ na dupẹ pupọ lọwọ Ọlọla Alec Douglas-Home fun ọro iyanju ti o ba wọn sọ ni o ba sọ fun gbogbo Ile, pe ki nwọn dide duro.

Lẹsẹkẹsẹ na ni gbogbo enia dide duro, Ọlọla na dupẹ lọwọ wọn, o si jade lọ si ode lati tun lọ ṣe awọn iṣẹ miran ti o tun wa niwaju rẹ.

Nigbati o ti lọ tan, ni awọn ọmọ Ile Igbimọ na wa joko olukuluku si aye rẹ.

Bi Ọlọla na ti fi Ile Igbimọ na sile, ninu Ile iṣẹ Aṣofin Ijọba Gẹesi ni Naijiria ni nọmba 62, Campbell Street lo lọ taara lati lọ wo ile iṣẹ na.

Ni alẹ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni Ọlọla na de si Eko ni deede agogo mọkanla koja Iṣẹ ju medọgbọn.

O si ba awọn Oniwe irohin sọrọ lẹsẹkẹsẹ ti o ba Ọkọ Ofurufu de si Ikẹja ki o to wa si Eko ni oru ọjọ na.

Ọlọla na yio ba Ọkọ Ofurufu kuro ni Ikẹja ni owurọ yi pada lọ si Londọnu.

Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ki Ọlọla Alec Douglas-Home, ki Ọlọrun jẹki o pada de ile pẹlu alafia.

# KO F'OORUN !

APAPA:— Jinnijinni dabo gbogbo awọn enia ti nwọn ṣẹṣẹ ṣiwọ lenu iṣẹ wọn ti nwọn nlọ si ile ni deede agogo marun abọ irọlẹ ana ọjọ Ẹti ti iṣe ogunjọ oṣu yi nigbati okunrin kan, Ọgbẹni J. A. Adeoye, ti o ngbe nọmba 47, Muyibu Street, Apapa ṣubululẹ lojiji ti o si ku bamubamu.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa wipe, nibiti awọn enia na duro si ni ibudo mọto, ni nwọn ba ri mọto TAKISI kan, No L.C. 9457 ti nlọ si Apapa Ajegunlẹ nwọn si da a duro pe awọn ko ri bọọsi wọ ki o gbe awọn de Ajegunlẹ.

Bi nwọn ti nlọ ni awọn ọkunrin ti o wa ninu Takisi na ri wipe obinrin ti o joko ti wọn ninu mọto na kan oju, o kun ete, o kun eekanna ẹsẹ ati ti ọwọ re, o si fi awọn nkan olorun kun ara rẹ ati aṣọ ti o wọ sọrun.

('Vo oju ewe kẹfa)

## Awọn Ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ Mẹdogun F'ẹwọn Ọdun Ọdun Marundinladọta Danrawo

IBADAN:– Kẹkẹ pa ma gbogbo enia lẹnu nile kotu giga kan ni Ibadan bi adajọ agba Ọgbẹni J. A. Kester ti nda ẹwọn ọdun marundinladọta awọn ọmọ ẹhin ẹgbẹ alakukọ mẹdogun lati ilu atan Aiyegbaju ni agbegbe Ọshun, ni ijẹta.

Agbọ pe ẹsun ti afi kan awọn ọdaran yi ni pe nwọn fi ina jo ile awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ti nwọn si ja wọn lole larin ọdun 1961.

Obinrin kan ti owa ninu awọn odaran na Bintu Ilọri ti adajọ agba na sọ pe "Enia buruku ada ogun sile ni."

Adajọ ni ki on lọ san ọgọta ponun tabi ki ọlọ si ẹwọn osu mẹfa. Ọkọkan ninu awọn ọdaran mẹwa yi lo gba ẹwọn ọdun mẹrin mẹrin. Awọn ni Salawu Oni, M. Oke, S. Bamiduro J. Oluwo, Ọlayiwọla. S. Fashuyi, J. Oke, C Famedimu ati Felix Awẹ.

Awọn mẹta, S. Bamiduro S. Ojo ati Y. Alaojo gba ẹwọn ọdun kọkan ti ẹnikan yoku si gba ẹwọn osu mẹsan na ni Alphon Alegundeje.

Awọn mẹfa miran ni a gbọ pe Adajọ da silẹ pe ki wọn ma lọ ni alafia nitoripe kosi ẹri to lati le jẹ wọn niya.

Ninu idajọ rẹ Adajọ Agba Ọgbẹni Kester sọ pe on ripe lotitọ ni esun ti afi kan awọn ọdaran wọnyi.

Ati pe otitọ ni gbogbo wọn jọ gbero lati le fi epo pẹtirolu sun ile awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ni ọjọ na ti nwọn si fi ọgbọn ko wọn ni ẹru lọ.

Oki lọ fun wọn re iya ti on yio fi je wọn yio gbọdọ jẹ ẹkọ fun wọn lehin ọla.

---

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan 20 – Feb 18) Ọna nla yio ṣi silẹ fun ọ nipa iṣẹ rẹ gbogbo. gbiyanju ki o si ṣe akikanju.

PISCES (Feb 19 – March 20) Dupẹ fun ore nla ti Olọrun ti nṣe fun ọ, eyi yio fun ọ ni agbara lati koju si awọn aṣeku iṣẹ rẹ gbogbo.

ARIES March 21 – April 19) Ọjọ oni jẹ ọjọ ti o lewu diẹ fun ọ, ṣe agbara lati le ṣe awọn iṣẹ rẹ ni aṣeyori gbọ imoran awọn aladugbo rẹ.

TAURUS (April 20 May 20) Ọjọ oni dara fun ọ maṣe jafara lati dojukọ awọn aṣeti iṣẹ rẹ, ki o si mura lati dawọle ọna miran

GEMINI (May 21 – April 21) Oni jẹ ọjọ ire ati ọjọ alafia fun gbogbo awọn ti nrin irin ajo. Ẹo ṣe alabapade eniti ẹ o ro tẹlẹ, yio si ṣe nyin lore nla kan.

CANCES (June 22 - July 22)Yio jẹ iṣoro nla fun ọ lati le dojukọ ọna iṣoro kan ti ọrẹ rẹ yio dasile fun ọ. ṣugbọn bi o ko ba ṣiyẹ meji iwọ yio bori gbogbo iṣoro wọnyi.

LEO (July 23 - Aug 22) Ọjọ oni kise ọjọ wahala fun ọ maṣe gbiyanju lati lọ si irinajo rara. Gbiyanju lati bẹ awọn ọrẹ rẹ wo

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ọna idamu kan yio de ba ọ ti yio tile bi ọ ninu, ṣe suru ki o le dojukọ awọn ohun ti o yẹ ọ lati ṣe

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Bi o ba fẹ ṣe ohunkohun loni, yio dara fun ọ. Awọn iṣẹ rẹ gbogbo yio tẹ awọn oluba ṣiṣẹ pọ rẹ lọrun ṣe suru lati ma ba awọn enia sọrọ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 23) Oni yi dara fun ọ maṣe fi aye silẹ fun awọn agbọyisọyi. Gbiyanju lati dojukọ awọn iṣẹ aṣeti diẹdiẹ

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Suru ati irẹlẹ ọkan lo yẹ ọ loni ki o le ṣẹgun gbogbo awọn iṣoro ti o wa niwaju rẹ, Gba imoran kan ti ọrẹ rẹ yio gba ọ.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 19) Arẹ nla yio de ba ọ ṣugbọn ki o ba se suru, iwọ yio bori gbogbo iṣoro na. Mura ... lọ b... wọn enia rẹ wo

---

BERE OJULOWO EGBOGI:–

## Congreve's Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titu fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọru tabi amodi Inu sinnu ni gbakugba tabi ni ẹkọnkọn ẹhin-didun, ibadi wiwo tabi sisọn ẹ'ẹdudu lara tabi aikọfọ ẹje lara Inu gbigbona nigbakugba Igba-aya riru ọr u riro wiwo, didun arẹ atinu wa ti wa nfa oyi-oju Ilaogun ara jẹ ẹsẹ ara sisọn, gbori abi ẹelu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun tọju gbogbo Obinrin gegebi Ajọ fun ilera idi rọ ati orisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI ATI JỌ T WỌN NPE NI:–

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki aw n Orisirisi sọbirọki egbogi ti wọn uko wa risirsinyi to de awọn ag alagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi iwe egb gi yi bi otutu kọ ita, orẹrẹ lukuluku origbamen aibu ba nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danju ni bi oba ti ta de si ... ti o bọwọsọ ki o si ... u sare egbogi otutu ti o daju fun itoju eti riru tabi didun, to Akokoro. egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu ayọ-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọwa-ọfun didun ati orisirisi omiran pẹlu bere ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Mdicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Niger ..., (Oja Ita Faji)

---

### AKIYESI

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IṢORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI: —WOLI ORIOLOWO AKINDELE ADAGA COMPOUND RILE—ILUGUN VIA—IBADAN

---

## BI O BA NI Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**IWE Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE–IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16. Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN OWO POKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Danwa wi lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# Ogun Jija Fun Ẹsin Islam

Lati ọwọ MALAM SALAWU—DEEN, Omupo

Ikẹ ati ọla ko mọ ba Anabi wa, amin ọrọ mi ti yi duro lori ogun jija fun Ẹsin Anabi wa, Kurani mimọ ori 66 ẹsẹ 8 sọ pe, Iwọ Anabi ja awọn alaigbagbọ logun, awọn agabagebe, ninu Imọle gbogun ti wọn nitoripe ina jananmọ nibugbe wọn, eleyi ni apada si buburu, eleyi fi han gbangba pe a ni lati jagun fun igbega ẹsin Isilam.

Isẹ ẹnyin Alufa ati onimimọ olowo, gbajumọ, lọkunrin ati lobinrin paapa ẹnyin Alhaji a ni lati gbiyanju lati to ọna Ọlọrun ni. Iwọ onimimọ fi mimọ rẹ ṣe ti Oluwa, olowo fi owo rẹ ṣe ti Oluwa, mọ fi agbara ati gbajumọ rẹ mọ Oluwa Alhaji ti ki de ile Oluwa kodara.

A ni lati fi gbogbo agbara wa se ti Oluwa, Iwọ oni mimọ, iwọ ti fi gbogbo eleyi silẹ keeta, irọ, ole, ijanba soke-sodo lo ngbe dani Iwọ Alhaji onisina, purọ danadanı o ye ki a pa gbogbo eleyi ti si apakan. Ẹ je ki a ṣe nkan ti Ọlọrun fẹ ki a ṣe.

Ẹ je ki a jagun Isilamu le di gbigbe ga larin orilẹ-ede wa Kurani mimọ ori 49 ẹsẹ 15 sọ bayi awọn ti o daju ni awọn ti o gbagbọ lododo si Ọlọrun ati ojisẹ rẹ, lẹhin na ti ko ṣe iye meji ti onsi ngbiyanju fun isin pẹlu dukia rẹ ati ẹmi rẹ fun ilọsiwaju aju ọna isin ti Ọlọrun.

## Fixed Odds Special

BY POOLS—STAR

PERM ANY 3 FROM THESE:—

Nott F.
Sheff United
Bournemouth
Colchester
Oldham
Millwall

NEXT BEST:-

Blackburn, Aldevsort, and Hartpools

4 AWAYS POOL:-

EVERTON
Man United
Swansea
Wallsall
Brighton
Workington
Patrich

E Fife

20 Failling to Draw

| | |
|---|---|
| Stole | Leeds |
| Northampton | Watford |
| Bradford | Carlisle |
| Gillingham | Airdrie |
| Rangers | Hull |
| Hibernian | Aston Villa |
| Swidow | Mau City |
| Exter | St. Johnston |
| Alloa | Chelsea |
| Bristol R. | Sunderland |

SPECIAL NAPS

| | |
|---|---|
| Blackburn | Millwall |
| Colchester | St. Johnston |
| Nott. F. | |

Try your luck this might be your lucky week.

## Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ ... iba ṣe eyiti o ti ... tabi eyiti oṣi wa laaye ... bi nwọn ti se te ... ọkan do tawi eyikeyi ninu Itan Isẹdalẹ Yoruba, ki eluwarẹ kọ ọ sọwọ.

... tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid—Ul—Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos On Sunday 26th April 1964 (Sunday Odun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, sieze this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tikets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices. Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta.

BERE OJ... /O EGB GI AWỌN FARANṢE TI NWỌN IPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALET**

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yen rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irulẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Iatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pelu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mo tonitoni pelu.

Ṣa dan gore kan wo iwọ yio si ma a tohiın rẹ fun ẹlomiran pelu

Bere egbogi ajẹbina Payal ... wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street Yaba

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 561 SATURDAY MARCH 21, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba


16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.


# EGBẸ DẸMỌ FẸ KI ÒKPÀRA FI IPO RẸ SILẸ

IBADAN:— Ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ti Oloye S. L. Akintọla ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣẹṣẹ dasilẹ ti kesi Dọkita Michael Okpara ti iṣe Alakoso Ijọba ipinlẹ Ila Orun Naijiria lati fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Olori ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni were were, ati ipo rẹ gẹgẹbi Alakoso Ijọba Ipinlẹ na.



Dokita M. I. OKPARA

Iwe ipe yi ti ile ẹgbẹ Dẹmọ jade ni ọjọ ṣẹgun ti iṣẹ ọjọ kejidinlogun oṣu yi, ninu eyiti ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na Ọgbẹni N.A B Kotoyẹ ti iṣe ọkan ninu awọn ọmọ ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Iwọ Orun fi ọwọ si

Ọgbẹni Kotoyẹ fi ẹsun kan Dọkita Okpara pe, o ti fẹ lati ṣi gbogbo orilẹ-ede Naijiria lọna, nipa bi o ṣe sọ pe ohun ko gba abayọri eto ikania ti o jade laipẹ yi Ọgbẹni Kotoyẹ ṣe alaye wipe gbogbo awọn ohun ti o nṣẹlẹ nisisiyi fi han wa dajudajupe Dọkita Okpara pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ (NCNC) ti nwọn nṣe Alakoso ninu Apapọ Ijọba ilẹ wa ati awọn ti nwọn ti wa ni Alakoso ni ile igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun ko dọgba lori abayọri eto ikania rara.

Ọgbẹni Kotoyẹ tun fi han pe, bi awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N. C N. C.) ti nwọn wa ni ile Igbimọ aṣofin ti Ipinlẹ Ila Orun ti nta ko abayọri eto ikania yi, bẹni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti o wa ni ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria nfara mọ ọ.

Otun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, dipo ki Dọkita Okpara maa ba awọn ọmọ lẹhin rẹ wi. Ọlọla Abubakan Tafawa Balewa tiiṣe Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ni o ntako lori ọrọ na,

Ni ipari, Ọgbẹni Kotoyẹ kesi Dọkita Okpara lati yara tete fi aye rẹ sile,, ki o ma ba ṣe ṣi awọn enia orilẹede yi lọna.



Oloye S. L. AKINTỌLA


## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba, lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbodi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere iko otutu igba-an kọ agbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pẹlu kelẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan abi loru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)


LATI OJU EWE KINI

Nigbati awọn ọkunrin na ri obinrin yi, nwọn dakẹ nwọn dakẹti, ni nwọn ba nfi obinrin na ṣe yẹyẹ nwọn si npe ni "KOF'OORUN"

Nigbati nwọn de ijana Ijora ati apapa inu bi Obinrin na ni nwọn ba bẹrẹsi ija, nwọn si nlu ara wọn ninu TAK'SI ni, Oni mọto ba da TAKISI rẹ duro, Ṣugbọn awọn Ọkunrin na ko ye ba "K'FOORUN" na ja, ni Onitakisi na ba gba Ọkunrin na ni eti.

Nigbati ori wipe awọn ọkunrin ati obinrin na fẹ pa ara wọn ni oba gbe wọn lọ si Tesan awọn ọlọpa Ijọra lati lọ fi ọran na ha awọn ọlọpa nitoripe nwọn ti lu ara wọn pupọ ninu mọto.

Ṣugbọn bi awọn ero inu mọto na ti sọkalẹ ninu Takisi, ti nwọn si fẹ ma a gun ori oke ile pẹtẹsi Tesan awọn ọlọpa Ijọra lọ ni ọkunrin na Adeoye ba ṣubu lulẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ọlọpa ti owa ni Tesan sare jade ati awọn enia ti nwọn wa ni Tesan. Bi nwọn ti gbe ọkunrin na de ile Iwosan ni oba dakẹ osi ta teru nipa.

Ọga awọn Ọlọpa na sọ fun Ejọngboro wipe awọn ti mu obinrin na ti nwọn pe ni "KOF'OORUN" ati onimọto Takisi na lati gbọ ti ẹnu wọn.

Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹ o ma a gbọ o.


Pinted and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P O. Box 1495Phone 21985
Ed'tor: TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yaba Lagos (21/3/64)